Ẹ̀dà ỌFẸ́ ti Ìrànlọ́wọ́ Owó Ìwé Ìbèrè, Ọ̀fin Ìrànlọ́wọ́ Owó, Ìsọníṣókí Èdè Tódán Mọ́rán, àti Ọ̀fin Ìdíyelé & Gbígbà wà nílẹ̀ ní Èdè Gẹ̀ẹ́sì, Sipaniṣi, àti àwọn èdè míràn tó bá àmúyẹ tí a ṣàlàyé nínú Ofin Ìrànlọ́wọ́ Owó mu nípasẹ̀:

- Kíkàn sí Ẹ̀ka Iṣẹ́ Ìgbaniwọlé/ Ìforúkọsílẹ̀
- 713.338.5502 tàbí 1.800.526.2121, ẹ̀yàn 5
- Bíbèrè fún ìwé ìbèrè nípa í-meèlì:
  909 Frostwood
  Attn: PBS Financial Assistance
  Houston, TX 77024
- Gbígba ìwé ìbère kan sílẹ̀ láti Memorial Hermann Health System ojúlé wẹ́ẹ̀bù: http://www.memorialhermann.org/financialassistanceprogram/

**Memorial Hermann Health System**
Láti rí bóyá o yẹ fún ìrànlọ́wọ́ owó, Medicaid, Medicare, tàbí àwọn ètò míràn, àti fún ìrànwọ́ ọ̀rọ̀ àṣírí lọ́fẹ̀ẹ́ láti bèrè, kàn sí:

**Patient Business Services**
909 Frostwood Dr., Suite 3:100
Houston, TX 77024
Attention: PBS Financial Assistance

Fóònù: 713.338.5502 tàbí
1.800.526.2121, ẹ̀yàn 5
Í-meèlì:
Patient.Billing@memorialhermann.org

Ọjọ́ Ẹtì: 8 òwúrọ̀ – 5 ìrọ̀lẹ́
Ọjọ́ Ajé - Ọjọ́bọ̀: 8 òwúrọ̀ – 7 ìrọ̀lẹ́

Déètì Ẹ̀yà Ọjọ́ 14 Oṣù kọ̀kanlá, 2017

MEMORIAL HERMANN

4411107YOR - Yoruba

# Ìsọníṣókí Ìrànlọ́wọ́ Owó Aláìsàn

## Ìsọníṣókí Èdè Tódán Mọ́rán



Àwọn Ìbéèrè Pàtàkì Díẹ̀ Tí A Dáhùn:

- Irú àwọn iṣẹ́ wo ni ó kàn?
- Báwo ni mo ti le bèrè fún ìrànlọ́wọ́?
- Tani ó yẹ fún ìrànlọ́wọ́?
- Kínni àwọn òdíwọ̀n owó-àpawọlé?
- Tí n kò bá kójú ìwọ̀n fún òdíwọ̀n owó-àpawọlé ńkọ́?
-Níbo ni mo ti le rí ìwé ìbèrè láti le bèrè?

MEMORIAL HERMANN

# Òfin Ìrànlọ́wọ́ Owó (FAP)

Memorial Hermann Health System ìrànlọ́wọ́ fún àwọn òbí tó yẹ èyí tó dá lórí owó àpawọlé, bí ẹbí ti pọ̀ tó àti Ipele Àìní Ìjọba fún ìtọ́jú ilé-ìwòsàn tó ṣe pàtàkì èyítí- ó jẹ́ pàjáwìrì tàbí ìtọ́jú ìlera tí a ṣe ìdínwó fún ní kíkún tàbí díẹ̀. Àwọn aláìsàn tí ń wá ìrànlọ́wọ́ owó gbọ́dọ̀ bèrè fún ètò náà, èyítí a sọ nísókí nínú àkọsílẹ̀ yìí.

## Irú Àwọn Iṣẹ́ wo ni ó Kàn?

Òfin Ìrànlọ́wọ́ Owó (FAP) kan àwọn iṣẹ́ pàjáwìrì àti ìtọ́jú ìlera tó ṣe pàtàkì èyítí a pèsè ní Memorial Hermann Hospital.

Òfin Ìrànlọ́wọ́ Owó KÒ KAN: àwọn ìlànà òge, àwọn iṣẹ́ ni a pesè nípasẹ̀ àwọn dókítà àti àwọn olùpèsè míràn tó tọ́jú rẹ ní Memorial Hermann Hospital ṣùgbọ́n tí Ilé-ìwòsàn náà kò gbà síṣẹ́, tàbí àwọn olùpèsè tó díyelé yàtọ̀ sí ti Ilé-ìwòsàn fún àwọn iṣẹ́ wọn.

## Bí a ti le Bèrè

Òfin Ìrànlọ́wọ́ Owó àti Ìwé Ìbèrè ni a le fọwọ́ gbà, nípasẹ̀ í-meèlì, nípasẹ̀ ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ àti láti ojúlé wẹ́ẹ̀bù Memorial Hermann.
Parí ìwé ìbèrè náà, ṣàfikún àwọn ìwé àkọsílẹ̀ tí wọ́n bèrè kí o sì fàá kalẹ̀ sí Ẹ̀ka Iṣẹ́ ti Ìforúkọsílẹ̀ / Ìgbaniwọlé Ilé-ìwòsàn tàbí sí àdírẹ́sì tí a kọ sẹ́yìn ìwé-ìléwọ́ náà.

## Àwọn Òdíwọ̀n Owó-àpawọlé

Ọ̀kan nínú àwọn ohun àmúyẹ ni owó-àpawọlé tó dá lórí tàbílì ìsàlẹ̀:

| ÀWỌN ÌTỌ́NI ÀÌNÍ 2018 | |
|---|---|
| Àwọn ènìyàn tó wà nínú ẹbí/mọ̀lẹ́bí | Owó-àpawọlé láàrín Ọdún |
| 1 | $ 12,140 |
| 2 | $ 16,460 |
| 3 | $ 20,780 |
| 4 | $ 25,100 |
| 5 | $ 29,420 |
| 6 | $ 33,740 |
| 7 | $ 38,060 |
| 8 | $ 42,380 |

Fún ẹbí/mọ̀lẹ́bí tó ní ju ènìyàn 8 lọ: ṣàfikún $4,320 fún ẹnìkọ̀ọ̀kan tí a ṣàfikún.

## Tani ó yẹ fún Ìrànlọ́wọ́ Owó?

Iye owó fún ìrànlọ́wọ́ owó dá lórí owó-àpawọlé rẹ, bí ẹbí rẹ ti pọ̀ tó àti Ipele Àìní Ìjọba. Àwọn aláìsàn tó ní owó-àpawọlé ẹbí tó jẹ́ 200% ti Ipele Àìní Ìjọba tàbí tó kéré jù bẹ́ẹ̀ lọ le yẹ fún ẹ̀dínwó 100%. Àwọn aláìsàn tó ní owó-àpawọlé ẹbí tó ju 200% ti Ipele Àìní Ìjọba lọ le yẹ fún ẹ̀dínwó.

Wo ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé nínú òfin náà ní: **http://www.memorialhermann.org/financialassistanceprogram/**

Àwọn aláìsàn tó yẹ ni a ko ní díyelé mọ́ fún pàjáwìrì tàbí ìtọ́jú ìlera míràn tó ṣe pàtàkì ju Iye Tí A ń Bèrè (AGB) lọ́wọ́ àwọn aláìsàn tó ní ìdójútòfò.

Àwọn ọ̀nà ìdámọ̀ àwòrán wọ̀nyí ni a ń gbà fún ẹ̀rí ìdánimọ̀:

- Ìwé ìgbàláyè awakọ̀ ti ìjọba tàbí káàdì ìdánimọ̀
- Káàdì ìdánimọ̀ tí ọmọ ilé-ìwé
- Ìwé ìrìnà (US tàbí òkèrè)
- Ìwé ìrìn-àjò ti U.S.
- Káàdì ìdánimọ̀ èyítí Aṣojú Ìjọba Ilẹ̀ Òkèrè fúnni
- Káàdì Ìsanwó (pẹ̀lú fọ́tò)